# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Ose Keta: Osu Kini Ojo Kedogun, 2017

## Akori oro: Igbala Olorun – Apa keta

## Eko kika: Isaiah 61: 1-3

Akori ti o kan lati soro nipa re ni ipolongo Igbala Olorun fun gbogbo araiye, ki gbogbo okan le ni anfani lati ko ipa ninu Igbala ofe yi.

### Ipolongo Igbala

O je ojuse fun gbogbo awa Kristiani lati polongo Igbala Olorun fun gbogbo eya, fun okunrin ati obirin, ati fun gbogbo orile-ede. Idi niyi ti Jesu Kristi fi pase pe "E lo si gbogbo aiye, ki e si ma wasu Ihinrere fun gbogbo eda" **Marku 16: 15**.

**Olorun fi apere le'le:** Olorun fi apere le'le fun awa eda-enia lati tele ilana nipa Igbala re. O si se afihan agbara ati ife ti o ni lati gba gbogbo araiye la. Iwe mimo wipe "Oluwa ti so Igbala re di mimo; ododo re li o ti fi han nigbangba li oju awon keferi. O ti ranti anu re ati otito re si awon ara ile Israeli; gbogbo opin aiye ti ri Igbala Olorun wa" **Orin Dafidi 98: 2-3**. Kini ohun ti o nduro de? "O ku si owo re" torina tele isise ati ilana Olorun.

**Fi Igbala Re han ni ojojumo:** Bi o ba je okan lara awon eleti omo, iwo yio polongo Igbala Baba re ti mbe ni orun lojojumo. Iwo yio jewo Igbala re nigbati o wo ati nigbati ko wo. Bibeli wipe "E korin si Oluwa, fi ibukun fun oruko re; e ma fi Igbala re han lati ojo de ojo" **Orin Dafidi 96: 2, 1 Kronika 16: 23**. Nitorina, mase je oniwa imotara-eni-nikan, so fun awon enia nipa Ihinrere Igbala Olorun. Je ki won mo wipe Olorun nikan ni Igbala re, ki o si ti ipa be, jere awon okan sinu Ijoba Olorun. Fi mule fun awon eda-enia wipe Olorun ni agbara ati iwalaaye re, O si ti ipa be di Igbala aiyeraye re **Isaiah 12: 2**.
So jade fun awon enia wipe Oluwa ni imole re ati Igbala re, torina iwo ki yio beru tabi ni ifoya awon enia **Orin Dafidi 27: 1**. Ri daju wipe awon oro ti o so jade mu eso wa, ki awon enia ba le se afarawe re nipa fifi Olorun nikan se Igbala won.

**Agogo Igbala:** Ohun meji se pataki nigbakugba ti o ba nkede Ihinrere Igbala Olorun. Awon na ni Bibeli mimo ati agogo Igbala. Ni ode oni opo awon Kristiani ni won ko mo agbara ati riri Bibeli mimo ti ise Iwe aiyeraye. Opo ninu awon kristiani ni won ti fi foonu tabi komputa ropo Bibeli won, awon wonyi nlo

si ile-ijosin pelu foonu tabi komputa ni aisi Bibeli; iru awon enia wonyi gbodo dekun fun iwa buburu yi **Orin Dafidi 116: 13**. Ni igbakugba ti o ba nse ise ijere okan, ti o si nkede Ihiunrere Igbala Olorun lati jere okan sinu ijoba re, o ni lati mu Bibeli ati agogo Igbala dani; bikosebe o ntan ara re ni.

## Awon apere Igbala ti ara

Ao soro nipa die ninu awon Igbala ti ara lati inu Bibeli.

**Igbala ni Okun pupa:** Lehin ti awon omo Israeli fi ile Egipti sile, Farao ati awon omo-ogun re lepa won de Okun Pupa. Ni Okun Pupa Mose wipe ″E ma beru, e duro je, ki e si ri Igbala Oluwa, ti yio fi han yin li oni: nitori awon ara Egipti ti eyin ri li oni yi, eyin ki yio si tun ri won mo lailai". Olorun pin Okun Pupa ni iya si meji fun awon omo Israeli lati rin lori iyangbe ile ni arin Okun Pupa. Farao ati awon enia re tele awon omo Israeli wo inu Okun Pupa, won si segbe sibe, nitoriti Oluwa da sisan Okun Pupa pada si ipo re **Eksodu 14: 13**.

**Igbala ti Juda:** Igbala Olorun ni o gba awon enia Juda lowo omo Ammoni ati Moabu ati awon ara oke Seiri. Emi Oluwa bale Jahasieli, o si sotele wipe "Eyin ko ni ija ni oran yi; e tegun, e duro je, ki e si ri Igbala Oluwa lodo yin, iwo Juda ati Jerusalemu: e mase beru, beni ki e ma si se f'oya: lola, e jade to won: Oluwa yio si pelu yin". Awon enia Juda segun awon omo Ammoni ati Moabu ati awon ara oke Seiri nipase kiko orin iyin nikan **2 Kronika 20: 17**.

**Igbala ti Danieli:** Oluwa gba Danieli la, nigbati a gbe e so sinu iho kiniun, nitoripe, ko da ese bikosepe o se ohun ti o se itewogba si Oluwa nipa gbigbadura si Olorun. Oba ko le sun, o lo si ibi iho kiniun ni afemoju, o si wipe "Danieli iranse Olorun alaaye, Olorun re, eniti iwo nsin laisimi, ha le gba o lowo awon kiniun bi?″ O je iyalenu fun oba nigbati Danieli da lohun, nitoripe o lero wipe yio ti ku **Danieli 6: 7-23**.

## Awon apere Igbala ti Emi

Ao mu die ninu awon apere Igbala emi lati inu Bibeli ti ao fi soro. Awon enia ti a ko oruko won sinu Iwe Iye ti won yio jogun ijoba Olorun **Ifihan 21: 27**.

**Awon Aposteli ni aika Judasi:** Ni igba ise-iranse Jesu Kristi Oluwa ninu aiye, O kilo fun awon adorin ti o ran jade lati lo wasu ironupiwada. Awon wonyi fi ayo pada, won nwipe "Oluwa, awon emi esu tile foribale fun wa li oruko re" **Luku**

**<u>10: 17</u>**. Jesu dahun wipe "E mase yo si eyi, pe, awon emi nforibale fun yin; sugbon e kuku yo, pe, a ko oruko yin sinu Iwe Iye ni orun" atipe e o jogun ijoba Olorun **<u>Luku 10: 20</u>**.
Gbogbo awon aposteli won ni Igbala emi, ti won si jogun ijoba Olorun, debipe a ko oruko won si ara ipinle Jerusalemu titun ilu Olorun; ni aisi oruko Judasi Iskariotu eniti o fi Jesu han **<u>Ifihan 21: 14</u>**. Sugbon, a fi oruko Mattia ropo oruko Judasi **<u>Ise awon Aposteli 1: 23-26</u>**.

**<u>Igbala Sakeu:</u>** Jesu Kristi Oluwa fun Sakeu agbowode ni Igbala aiyeraye, nitoripe o ronupiwada, o si pese okan re sile fun Igbala Olorun. O nfe lati ri Kristi, sugbon nitoripe o je enia kukuru, o gun ori igi sikamore. Nigbati Olugbala de ibe o wipe "Sakeu, yara, ki o si sokale; nitori emi ko le saiwo ni ile re loni" **<u>Luku 19: 1-8</u>**.

## <u>Awon iwa ti o nmu Igbala wa</u>

Opolopo iwa ni o le mu Igbala Olorun wa tabi ki o jeki Igbala re pe titi ninu aiye re. Iwonba ninu won ni ao menuba.

**<u>Gbe Olorun ga ki o si ma yo ninu Re:</u>** Awa enia ti a nfe ifarahan Igbala Olorun ninu aiye wa, ni lati gbe Oluwa ga ju adidun aiye ati ohun asan aiye lo. A ni lati gbe Oluwa ga ju ebora, tabi ere-gbigbe, tabi awon emi-aimo, tabi orisa ati esu lo. <u>Labe-botiwukori a ko gbodo gbe awon asa ati ise-se wa ga ju Olorun lo</u> **<u>Orin Dafidi 18: 46</u>**.
Nitorina, ma fi ope ati iyin fun Oluwa nigbagbogbo. Gbe Olorun ati oruko mimo re ga ju ohunkohun ninu aiye lo. O se pataki fun o ki o ma yo niwaju Oluwa, ki Igbala re le de kiakia. Mase ya abara-moreje enia, dupe ki o si se ajoyo ki Igbala Re ba le pe titi ninu aiye re **<u>Orin Dafidi 35: 9</u>**. Ma yo ninu Igbala Olorun ki Satani ba le fi ibinuje sa kuro lodo re.

**<u>Ronupiwada awon ese re:</u>** Li aisi ironupiwada, ko le si Igbala, nitoripe ohun ti Olorun nfe lati odo re ni irobinuje okan ati irora aiya, eyiti yio yori si Igbala. Olorun kosi ni gan eyi **<u>Orin Dafidi 51: 17</u>**.
Ni afikun iru ibanuje ti Olorun fe ki a ni, je eyiti yio muwa jina/takete si ese, ti yio si yorisi Igbala. Kosi abamo fun iru ibanuje yi, sugbon ibanuje ti aiye koni ironupiwada, besini eleyi a ma yorisi iku nipa ti Emi **<u>2 Korinti 7: 10</u>**. Bi o ba nfe Igbala, ni ibanuje ti iwa-bi-Olorun ti o nmu ironupiwada wa, eyiti o ma nyorisi Igbala Olorun.

**Iberu Olorun:** Opolopo orile-ede ni agbaiye ni won ko si ni ipo ti Eleda to won si, nitoripe won ko beru Olorun sugbon won gbekele agbara tikalara won. Awon ti won beru Olorun nikan ni yio ri Igbala gba. Idi niyi ti Bibeli fi wipe "Nitoto Igbala re sunmo awon ti o beru re; ki ogo ki o le ma gbe ile won" **Orin Dafidi 85: 9**. Orile-ede ti o ba nfe Igbala Olorun ni lati beru Re e, ki o ba le fi ogo kun ile won.

**Iyasimimo ati igbagbo:** Wiwa ni mimo ati igbagbo je ara awon ohun ti enia nilo fun Igbala. Baba wa ti mbe ni orun ti yan awa kristiani si Igbala ninu isodimimo Emi ati igbagbo otito **2 Tessalonika 2: 13**. Iwo ko gbodo tun so ara re di eleeri, sugbon di igbagbo re mu sinsin, ki Igbala Olorun ba le farahan ninu aiye re.

**Sin Olorun ninu ewa iwa mimo:** Enikeni ti o ba fi iwa-bi-Olorun kun sisin Olorun ninu ewa iwa mimo, on ni ao fi Igbala wo gegebi aso. Olorun yio lo iru awon enia yi fun Igbala awa eda-enia. Iwe mimo wipe "Emi o si fi Igbala wo awon alufa re: awon enia mimo re yio ma ho fun ayo" **Orin Dafidi 132: 16**. Bi o ba fe wa lara awon ti ao fi Igbala wo, ti ao si lo fun Igbala awon enia jakejado agbaiye, fi iwa-bi-Olorun kun sisin Olorun ninu ewa iwa mimo.

**Yera fun iwa buburu:** Sa fun ise ibi, kehin si iwa buburu, wa ilana Oluwa ri, ki o si ma pa awon ofin re mo. Nigbana ni Igbala Re yio farahan ninu aiye re **Orin Dafidi 119: 155**. Bi o ko ba fe ki Igbala jina si o, sugbon ki o wa nitosi re. Beru Oluwa, ki o si ko iwa buburu sile.

**Igbala awon elomiran:** Mase je oniwa imotara-eni-nikan. Bi o ba ti nronu tabi ro'ri lori oro ara re, jeki Igbala awon elomiran se koko ni ookan aiya re. Iwe Isaiah wipe "Ke rara, mase dasi, gbe ohun re soke bi ipe, ki o si fi irekoja awon enia mi han won, ati ile Jakobu, ese won" **Isaiah 58: 1**. Tiraka, ki o ri wipe o gba emi kan la kuro lowo iku; ki a le ti ipa re bo opolopo ese mole, ti yio si muki Olorun fun o ni ere **Jakobu 5: 20**.

**Ke pe oruko Oluwa:** Niwon igbati kosi oruko miran labe orun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a fi le gba wa la bikose Jesu Kristi. Torina, kepe oruko Jesu Kristi Oluwa ki a le gba o la **Romu 10: 13, Ise awon Aposteli 2: 21**. Mase pe oruko awon orisa tabi ere-gbigbe tabi alujonnu tabi emi-aimo, nitoripe oruko Jesu Kristi nikan ni o le fun o ni Igbala.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Ose Kerin: Osu Kini Ojo Kejilelogun, 2017

## Akori oro: Igbala Olorun – Apa kerin

## Eko kika: Isaiah 61: 1-3

Ao bere abala ti o kehin ninu eko yi nipa bi igbagbo ti le mu ki enia di eni Igbala.

## Igbagbo ati Igbala

Bibeli wipe " li aisi igbagbo ko se ise lati wu Olorun, nitori eniti o ba nto wa a, ko le sai gbagbo pe o mbe, ati pe on ni olusesan fun awon ti o fi ara bale wa a" **Heberu 11: 6.**

**Igbala wa nipa Igbagbo ati ise:** Niwon igbati a nilo igbagbo lati wu Olorun, ati lati ni ibasepo pelu re; ise je koko lati se afihan igbagbo wa, nitoripe igbagbo li aisi ise asan ni **Jakobu 2: 20.** Nitorina, igbagbo ati ise se pataki ki a ba le gba o la. Fun Igbala Olorun lati farahan ninu aiye re, o nilo igbagbo ati ise **Jakobu 2: 14-17.**

**Adura Igbagbo nmu Igbala wa:** Ohunkohun ti o ndamu re ati bi otiwu ki isoro re tobi to, Olorun ni agbara lati yanju won gegebi ese Bibeli ti o wipe " ko si ohun ti Olorun ko le se" **Luku 1: 37**. Torina, gbadura si Olorun pelu igbagbo, ki Igbala re le farahan, ki ekun re ba le di erin; ki ibanuje re si di ayo; nitoripe gbogbo wahala re ni yio di itan **Jakobu 5: 15.** Adura igbagbo re ko gbodo je ti iwosan nikan toripe o ni agbara lati yanju gbogbo isoro re, ki oke-isoro re ba le di petele.

**Igbala daju ti o ba rin ninu Igbagbo:** Igbala daju fun gbogbo okan ti o ba nfi igbagbo ba Olorun rin. Abrahamu gba Olorun gbo, a si ka a si fun u li ododo **Galatia 3: 6**. Iwo na bere sini rin irinajo-kristiani re pelu igbagbo, ki Olorun le ka a si Igbala fun o. Niwon igbati a wa ni igba-ikehin, Igbala re sunmo etile ju igbati o ti gbagbo lo. **Romu 13: 11.** Ji loju oorun-ese ti o wa, ki o si bere sini fi igbagbo ba Olorun rin, ki Igbala re ba le daju.

## Awon Iyorisi

Lotito, o di dandan fun wa lati menuba idajo ati ijiya ti yio wa si ori awon enia ti won ba ko Igbala-ofe Olorun sile. Okan ninu awon iyorisi iwa-aibikita yi ni ao soro nipa re, nitoripe ohun ti mo gbadura fun odun titun yi kise ijiya tabi idajo Olorun; bikose ironupiwada ati Igbala okan awon enia.

**Ibinu Olorun yio ru:** Ibinu Olorun yio ru si awon enia ti won ko ni igbagbo ninu re,ti won ko si gbekele Igbala re. Ibinu Olorun yio dide si iru awon enia be, debipe ina-emi yio ran, ti yio si mu ki aiye won polukuru-musu; ti yio si mu ki iwa-laaye won wa ninu ewu **Orin Dafidi 78: 21-22.** Mo gbadura wipe ibinu Olorun ko ni wa sori wa, beni Ina re koni sise-lodi si wa; sugbon anu ati ojurere Olorun yio pe titi lailai ninu aiye wa.

## Awon Ere

Ao se ayewo awon ere ti o wa ninu Igbala Olorun, lati fi Igbagbo awon ayanfe mule.

**Olorun yio gbesan re:** Olorun ni itara fun Igbala awon enia re. Idi eyi ni o fi ni iyara ati igbona-okan lati gba won la. Iwe mimo wipe "Iwo jade lo fun Igbala awon enia re, fun Igbala eni atororosi re; iwo ti sa awon olori kuro ninu ile awon enia buburu, ni fifi ipinle han titi de orun" **Habakkuku 3:13**. Niwon igbati o ba je olotito si Olorun, ti o si di igbagbo re mu, Olorun yio gbesan lara awon ota re, fun gbogbo ise-ibi ti won ti se si o.

**Olorun ko ni sinmi titi igbala re yio fi ma jo:** Niwon igbati o je ife-inu Eledumare ni wipe ki o di eni Igbala, torina, koni sinmi besini koni dake titi ododo re yio fi jade bi titan imole ati Igbala re bi fitila ti njo **Isaiah 62:1.** Bi o ba fe ki Olorun ni itara lori oro-aiye re, wa Igbala Olorun ri.

**Olorun yio se o ni ewa:** Inu Olorun yio dun si o, yio ni inudidun si iwa-laaye re, besini yio fi Igbala se o ni ewa **Orin Dafidi 149: 4.** Bi o ba fe ki Olorun fi isegun se o ni oso, ri wipe o ni Igbala. Olorun yio fi agbada-Igbala ati aso ododo wo o ni Bibeli wi **Isaiah 61: 10.** Bi o ba le ni igbekele ninu Igbala Olorun nikan.

**Igbala re nbo pelu ere:** Oluwa ti kede titi de opin aiye: O ti ranse si gbogbo ilu wipe Olugbala/Igbala mbo, ko ni san'wo wa, sugbon yio wa pelu opolopo ere fun awon eleti-omo; besini esan re wa niwaju re **Isaiah 62:11**. Se ayewo eri-okan re, se o wa lara awon ti yio gba ere nigbati Olugbala/Igbala re ba de?

**Oju ki yio ti o besini a ki yio yeye re:** Gbogbo okan ti o nwa Igbala Olorun ni oju ki yio ti, beni won ki yio damu. Nitorina ni igboya wipe Oluwa yio fi Igbala ainipekun gba o la, oju ki yio ti o, besini a ki yio yeye re **Isaiah 45: 17**.

**Igbala okan re:** Enikeni ti o ba gbekele Igbala Olorun, a ko ni ja-ku'le nitoripe ao fun won ni ere ti ise Igbala-okan won. Bibeli wipe opin igbagbo yin ni Igbala-

okan yin **1 Peteru 1: 9**. Bi o ba nfe Igbala-okan re, ti o si nfe jogun Ijoba Olorun; ri wipe o gbekele Igbala Re.

**Kristi yio pada wa fun Igbala re:** Gegebi a ti mo wipe a fi Kristi rubo lekansoso, lati ru ese opolopo. Sugbon yio farahan nigbakeji laisi ese fun Igbala awon ti nwo ona fun bibo re **Heberu 9: 28**. Jesu Kristi npadabo nitori re, nje o ti mura sile? Bi koba ribe yipada, ki o si ronupiwada ni kiakia.

**Awon adura**

Opolopo adura ni o wa ninu Bibeli ti a le gba, gegebi ipo ti enia ba wa, sugbon ao menuba die ninu won.

**Igba-kuro lowo awon ota:** Gba adura si Olorun wipe "Gba mi, Olorun Igbala mi, gba idile mi jo, ki o si gba wa lowo awon ota: ki awa le ma fi ope fun oruko re mimo, ki a si le ma sogo ninu iyin re **1 Kronika 16: 35**.

**Itusile kuro lowo idajo:** Bebe ki Olorun gba o lowo ebi-eje ati oniruru ese. Bere lowo Olorun Igbala re, ki o si ore-ofe sile ki ahon re ma korin ododo re kikan **Orin Dafidi 51: 14**.

**Igbesan:** So fun Olorun ki o fa oko yo, ki o si dena awon ti nse inunibini si o, ki o san esan ise won besini ki o wi fun okan re wipe "Emi ni Igbala re" **Orin Dafidi 35: 3**.

**Iranlowo:** Bebe ki Olorun yara lati ran o lowo kuro ni ipo kotemi-lorun ti o wa, nitoripe on ni Oluwa Igbala re **Orin Dafidi 38: 22**. Bere ki Olorun Igbala re, ran o lowo fun ogo oruko re: So fun ki o gba o, ki o si dari gbogbo ese ti ko jeki ohun rere je-yo ninu aiye re jin o. Ki o we gbogbo ese ti ndena igbega re nu, nitori oruko re **Orin Dafidi 79: 9**.

**Imubosipo:** Gbadura si Olorun ki o yipada si o, ki o si ka ibinu re kuro ninu aiye re. Bere ki o mu alafia ago-ara re pada bo sipo, ki o mu igbe-aiye re ninu Emi ati isakoso owo-nina re pada bo sipo nipa mimu ki ibinu re si o ki o da **Orin Dafidi 85: 4**. So fun Olorun ki o mu ayo Igbala Re pada bo sipo ninu aiye re, nipa mimu ki alafia joba ninu Igbeyawo/ile re, ki o si fi Emi ominira re gbe o ro **Orin Dafidi 51: 12**.

**Anu ati Ojurere:** Se eto adura ki Olorun le fi anu ati ojurere re han ninu aiye re. So fun ki o fi ife-aisetan han fun o, ki o si fun o ni Igbala aiyeraye **Orin Dafidi 85: 7**. Bere ki Olorun ki o sanu fun o, ki o si busi i fun o,ki o si se oju re ki o mole si

o lara; ki o si gbe ara re ga ninu aiye re, ki ona re ki o le di mimo li aiye, besini ki o lo o fun Igbala Re ni gbogbo orile-ede **Orin Dafidi 67: 1-2**.

**Ki o mase di eni-ikosile:** Bebe ki Olorun mase pa oju re mo kuro lodo re, besini ki o mase kehin si o; So fun ki o mase fi o sile tabi ki o fi ibinu sa o ti, nitori on ni iranlowo re. Bere ki Olorun mase ko o sile bi aso-gbigbo, sugbon ki o fi ibukun ati ire kun aiye re **Orin Dafidi 27: 9**.

**Igbega ati Itesiwaju:** Gbadura si Olorun ki o mu o kuro ni ipo kotemi-lorun ti nfa ibanuje ninu aiye re. Ki o si fi aye gba Igbala Re ti nmu igbega ati itesiwaju wa, eyiti yio gbe ogo mi leke lati sise-pipe **Orin Dafidi 69: 29**.

Lakotan, gbagbo ninu okan re si ododo ki a le da o la're, ki o si fi enu re jewo si Igbala **Romu 10: 10**. Olorun wipe "Emi mu ododo mi sunmo tosi; ki yio si jina rere, Igbala mi ki yio si duro pe: emi o si fi Igbala si Sioni fun Isreali ogo mi" **Isaiah 46: 13**.

**Edidi: Isaiah 49: 6** "O se ohun kekere ki iwo se iranse mi, lati gbe awon eya Jakobu dide ati lati mu awon ipamo Israeli pada: emi o si fi o se imole awon keferi, ki iwo ki o le se Igbala mi titi de opin aiye"